
**Nípasẹ Ààrẹ Dieter F. Uchtdorf**
Olùdámọ̀ràn Kejì Nínú Àjọ Ààrẹ Kínní



# Kún Ayé pẹ̀lú Ìfẹ́ ti Krístì

Nígbàtí a bá ronu nípa Kérésìmesì, a máa ńfi ìgbà púpọ̀ ronú nípa fífúnni àti gbígba àwọn ẹ̀bùn. Àwọn ẹ̀bún lè jẹ́ apákan àṣà àtọwọ́dọ́wọ́ ti a ṣìkẹ́, ṣùgbọ́n wọ́n lè ṣe àdínkú ìrọ̀rùn ipò ọlá ti àsìkò náà kí ó sì mú àkíyèsí wa kúrò ní ṣíṣe àjọ̀dún ọjọ́ ìbí ti Olùgbàlà wa ní ọ̀nà tí ó nítumọ̀.

ṅMo mọ̀ nípa ìrírí ti ara-ẹni pé àwọn Kérésìmesì tí ó le ní ìràntí jùlọ lè jẹ́ àwọn wọnnì tí ó ní ìrẹ̀lẹ̀ jùlọ. Àwọn ẹ̀bùn ti ìgbà èwè mi dájúdájú wà ní ìwọ̀ntúnwọ̀nsì nípa àwọn ọ̀ṣùwọ̀n ti òde òní. Nígbà míràn mo máa ńgba ẹ̀wù tí a ti túnṣe tàbí ìbọ̀wọ́ ti aláwẹ́ méjì kan tàbí àwọn ìbọ̀sẹ̀. Mo rántí àkànṣe Kérésímesì kan nígbàtí arákùnrin mi fún mi ní ọ̀bẹ onígi kan tí ó gbẹ́.

Kò níláti jẹ́ ẹ̀bùn tí ó níye lórí púpọ̀ láti mú kí Kérésìmesì ní ìtumọ̀. A ránmi létí ìtàn kan tí a sọ nípasẹ̀ Àlàgbà Glen L. Rudd, tí ó ṣiṣẹ́ sìn gẹ́gẹ́bí ọmọ ẹgbẹ́ ti Àádọ́rin láti ọdún 1987 sí ọdún 1992. Ní ọ́jọ́ kan ṣaájú Kérésìmesì ní ọdún méló kan sẹ́hìn, nígbàtí ó ńṣe àkóso ilé-ìṣura ti bíṣọ́ọ̀pù kan, ó ní òye láti ọ̀dọ̀ aṣaájú kan nínú ìjọ nípa ẹbí aláìní kan tí ó kó lọ sí ìlú ńlá náà láìpẹ́. Nígbàtí ó lọ bẹ ibùgbé wọn kékeré wò, ó rí ọ̀dọ́ abiléko ànìkànwà kan pẹ̀lú àwọn ọmọ mẹ́rin tí ọjọ́ orí wọn wà lábẹ́ ọdún mẹ́wá.

Àwọn ohun ti ẹbí yí nílò pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ débí wípé ìyá nàá kò lè ra àpẹjẹ tàbí ẹ̀bùn fún àwọn ọmọ rẹ̀ ní àkókò Kérésìmesì náà —kò tilẹ̀ lágbára láti ra igi kan. Arákùnrin Rudd sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ẹbí náà ó sì gbọ́ wípé àwọn ọmọbìrin kékèké mẹ́ta náà yíó nífẹ̀ẹ́ sí bèbí ìfiṣeré kan tàbí ẹranko kíkì. àtọwọ́dá. Nígbàtí ó bèèrè lọ́wọ́ ọmọdékùnrin ọlọ́dún-mẹ́fà ohun tí ó fẹ́, ọmọdékùnrin tí ébi npa náà dáhùn, "Èmi fẹ́ abọ́ oúnjẹ óòtì kan."

Arákùnrin Rudd ṣe ìlérí oúnjẹ óòtì fún ọmọkùnrin kékeré náà àti bóyá ohun míràn si. Nígbànáà ó lọ̀ sí ilé-ìṣura ti bíṣọ́ọ̀pù ó sì kó oúnjẹ jọ àti àwọn ohun èlò míràn lati bá àwọn àìní ẹbí náà pàdé lọ́gán.

Ní ààrọ̀ ọjọ́ náà gan an onínúre Ènìyàn mímọ́ Ọjọ́-ìkẹhìn kan ti fún un ní àádọ́ta dọ́là "fún ẹnìkan nínú àìní." Ní lílo ọrẹ náà, Arákùnrin Rudd gbé awọn ọmọ ara rẹ̀ méta dìde, ó sì lọ fún rírа ọjà Kérésìmesì— àwọn ọmọ rẹ̀ ńṣa àwọn ìṣeré-ọmọdé fún àwọn ọmọ aláìní náà.

Lẹ́hìn tí ó kó oúnjẹ, aṣọ, àwọn ẹ̀bùn, igi Kérésìmesì kan, àti àwọn ohun ọ̀ṣọ́ kún ọkọ náà, àwọn Rudd wakọ̀ lọ sí ibùgbé ẹbí náà. Níbẹ̀ wọ́n ran ìyá náà àti àwọn ọmọ rẹ̀ lọ́wọ́ láti ṣe àgbékalẹ̀ igi náà. Nígbànáà wọ́n gbé àwọn ẹ̀bùn sí abẹ́ rẹ̀ wọ́n sì fi ìdì oúnjẹ óòtì ńlá kan fún ọmọkùnrin kékeré náà.

Ìyá náà sọkún, àwọn ọmọ náà dunnú, gbogbo wọ́n sì kọrin Kéresìmesì kan. Ní alẹ́ ọjọ́ náà bí àwọn ẹbí Rudd ti kórajọ fún oúnjẹ alẹ́, wọ́n dúpẹ́ pé wọ́n lè mú ara yíyá Kérésìmesì bá ẹbí míràn àti láti ran ọmọkùnrin kékeré kan lọ́wọ́ láti gba abọ́ oúnjẹ óòtì kan.[1]

### Krístì àti Ẹ̀mí Fífúnni

Ronú nípa ọ̀nà ìrọ̀rùn síbẹ̀síbẹ̀ tí ó jẹ́ ti ipò ọlá tí Bàbá wa Ọ̀run yàn láti bọ̀wọ̀ fún ìbí Ọmọkùnrin Rẹ̀. Ní alẹ́

mímọ́ náà, àwọn áńgẹ́lì kò farahàn sí awọn ọlọ́rọ̀ ṣùgbọ́n sí àwọn olùṣọ́ àgùtàn. A kò bí Krístì ọmọ náà sínú ilé ńlá kan ṣùgbọ́n sínú ibùjẹ́ ẹràn. A kò we mọ́ aṣọ ọ̀gbọ̀ dára-dára ṣùgbọ́n àwọn aṣọ ọ̀já.

Ríṛọ̀rùn ti Kérésìmesì àkọ́kọ́ náà ṣebíi òjìji ìṣaájú ìgbé ayé ti Olùgbàlà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ó ti dá ayé, Ó rìn ní ilẹ̀ ọba ti ọlá ńlá àti ògo, tí Ó sì dúró ní apá ọ̀tún Bàbá, Ó wá sí ayé gẹ́gẹ́bí ọmọ aláìníràǹlọ́wọ́. Ìgbé ayé Rẹ̀ jẹ́ àwòṣe ti ìwọ̀ntúnwọ̀nsì ìwà ọlá, àti pé Ó rìn láàrin awọn òtòṣì, aláìsàn, onírẹ̀wẹ̀sì, àti ẹlẹ́rù wíwo.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ó jẹ́ Ọba kan, Kò bìkítà fún yálà ọ̀wọ̀ tàbí ọrọ̀ ti àwọn ènìyàn. Ìgbé ayé Rẹ̀, àwọn ọ̀rọ̀ Rẹ̀, àti àwọn ìṣe Rẹ̀ ojojúmọ́ jẹ́ ohun ìrántí ti ipò ọlá tí ó rọrùn síbẹ̀ tí ó jinlẹ̀.

Jésù Krístì náà, ẹnití ó mọ̀ ní pípé bí a ṣe lè fúnni, ṣe àgbékalẹ̀ àwòṣe fífúnni fún wa. Sí àwọn wọ̀nnì tí ọkàn wọ́n wúwo pẹ̀lú àdágbé àti ìbànújẹ́, Ó mú àànú àti ìtùnú wá. Sí àwọn wọ̀nnì tí ara àti inú wọn ní ìpọ́nlójú pẹ̀lú àìlera àti ìrora, Ó mú ìfẹ́ àti ìwòsàn wá. Sí àwọn wọ̀nnì tí ẹ̀mí wọn ní ìnira pẹ̀lú ẹ̀ṣẹ̀, Ó fi ìrètí, ìdáríjì, àti ìràpadà fún wọn.

Bí Olùgbàlà bá wà ní àárín wa lóní, a ó rí I ní ibití Ó máa ńwà nígbàgbogbo—ní ṣíṣe iṣẹ́ ìránṣẹ́ fún ọlọ́kàn tútù, onírẹ̀wẹ̀sì, onírẹ̀lẹ̀, onípọ́njú, àti òtòṣì ní ẹ̀mí. Ní àsìkò Kérésìmesì yí àti nígbàgbogbo, kí a lè fi fún Un nípa níní ìfẹ́ bí Ó ṣe fẹ́ni. Kí a lè rántí ìrẹ̀lẹ̀ ipò ọlá ti ìbí, àwọn ẹ̀bùn, àti ìgbé ayé Rẹ̀. Àti pé kí a lè, nípasẹ̀ íṣe ìwà rere tí ó rọrùn, ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́, àti àànú, kún ayé pẹ̀lú ìmọ́lẹ̀ ti ifẹ́ àti agbára ìwòsàn Rẹ̀.

**ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Wo Glen L. Rudd, *Ẹ̀sìn Mímọ́: Ìtàn ti àlàfíà Ìjọ láti ọdún 1930* (1995), 352–53; rí bákannáà Glen L. Rudd, "Abọ́ Oúnjẹ Óòtì Kan," *Ìròhìn Ìjọ,* Dec. 2, ọdún 2006, 16.

---

**Ẹ̀KỌ́ LÁTINÚ Ọ̀RỌ̀ YÍ**

Ààrẹ Uchtdorf kọ́ni pé a níláti tèlé àwòṣe fífúnni ti Olùgbàlà. Gbèrò lati bèèrè lọ́wọ́ àwọn ènìyàn tí ò bá bẹ̀wò kí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọ́n dárúkọ ẹ̀bùn kan tí Olùgbàlà ti fifún wọn, kí wọ́n sì sọ bí wọ́n ṣe lè lo ẹ̀bùn náà láti sin àwọn ẹlòmíràn. Fún àpẹrẹ, bí ọmọ ìjọ kan bá ní ìbùkún pẹ̀lú ìdánilẹ́kọ́ ti orin, arákùnrin tàbí arábìnrin náà lè lọ kọrin ìyìn fún díẹ̀ lára àwọn aládúgbò. O lè gbà láti kúnlẹ̀ nínú àdúrà pẹ̀lú àwọn wọnnì tí ò ńbẹ̀wò, ní ìbèèrè fún ìmísí nípa àwọn ẹ̀bùn èyí tí oó pín, bí oó ṣe pín wọn, àti pẹ̀lú tani. Padà ṣe àyẹ̀wò lórí èyíkéyí ìmísí tí o bá rí gbà.

## Ọ̀DỌ́

### Kọ́ ẹ̀kọ́ lati ínú Ìrírí Àwọn Ẹlòmíràn

Ààrẹ Uchtdorf nsọ̀rọ̀ láti inú ìrírí ara-ẹni nígbàtí ó ńkọ́ni pé "àwọn Kéresìmesì tí ó le ní ìrántí jùlọ̀ lè jẹ́ àwọn wọnnì tí ó ní ìrẹ̀lẹ̀ jùlọ." A lè kọ́ ẹ̀kọ́ púpọ̀ tó bẹ́ẹ̀ láti ọ̀dọ̀ ìran àtijọ́, ọ̀pọ̀ àwọn àgbàlagbà ti gbé ní àwọn àkokò ogun, àìníṣẹ́, àìsàn, tàbí àwọn àdánwò míràn. Bèèrè lọ́wọ́ àwọn ọmọ wọ́ọ̀dù tàbí ẹ̀ka rẹ tí wọn ti dàgbà láti sọ fún ọ nípa Kérésìmesì wọn tí ó nítumọ̀ jùlọ. O lè kọ àwọn ìtàn wọn sílẹ̀. Gbìyànjú láti kọ́ ẹ̀kọ́ láti inú àpẹrẹ wọn nípa dídojú Kérésìmesì yí kọ ṣíṣe iṣẹ́ ìsìn ní òdodo àti rírántí Olùgbàlà.

## ÀWỌN ỌMỌDÉ

### Àwọn Ẹ̀bùn láti ọ̀dọ̀ Jésù Krístì

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ńlo igi Kérésìmesì láti ṣe àjọ̀dún ìbí ti Jésù Krístì. Nígbà míràn àwọn ènìyàn máa ńgbé àwọn ẹ̀bùn sí abẹ́ igi náà fún àwọn ẹlòmíràn. Kínni awọn ẹ̀bùn tí Olùgbàlà ti fi fún ọ? Ya àwòrán igi Kérésìmesì tìrẹ pẹ̀lú ẹ̀bùn márùn ní abẹ́ rẹ̀. Ka àwọn orí ìwé mímọ́ ìsàlẹ̀ yìí kí o sì kun ẹ̀bùn kan fún orí ìwé mímọ́ kọ̀ọ̀kan. O lè fi awwọn ẹ̀bùn padà fún Jésù nípa wíwá àwọn ọ̀nà láti ran àwọn ẹlòmíràn lọ́wọ́.

Orin Dáfídì 33:6

Jòhánù 14:27

Jóhánù 15:9

2 Nífáì 2:8

3 Nífáì 15:9

© 2014 Nípasẹ̀ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ ìtumọ̀: 6/14.
Ìtumọ̀ ti *First Presidency Message, December 2014*. Yoruba. 10872 779

# Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ Tọrun ti Jésù Krístì: Aládé Àláfíà

Ìgbàgbọ́, Ẹbí, Ìrànlọ́wọ́

*Fi tàdúrà tàdúrà ka ohun èlò yĩ kí o sì wákiri lati mọ ohun ti õ ṣe àbápín rẹ̀. Báwo ni níní òye ìgbé ayé ati ojúṣe Olùgbàlà ṣe ńfikún ìgbàgbọ́ yin ninu Rẹ̀ ati kí ẹ sì bùkún awọn tí ẹ nṣe olùṣọ́ lé lórí nipasẹ̀ ìbẹniwò kíkọni? Fún ìwífúnni síi, lọ sí reliefsociety.lds.org.*

*Èyí ni apákan nínú oníruurú àwọn Ọ̀rọ̀ Ìbẹniwò Kíkọ̀ni tí ó ńfi awọn abala ti iṣẹ́ ìrànṣẹ Olùgbàlà hàn.*

"Olùgbàlà ni orísun àláfíà tòótọ́," ni Alàgbà Quentin L. Cook ti Ìyejú Àwọn Àpọ́stélì Méjìlá sọ. "Àní pẹ̀lú àwọn àdánwò ìgbé ayé, nítorí ti Ètùtù Olùgbàlà àti ore ọ̀fẹ́ Rẹ̀, ìgbé ayé ódodo ní yíò fi àlá-fíà ti ara-ẹni ṣe èrè jẹ."[1] Níní òye pé Jésù Krístì ni Aládé Àlàfíà lè ràn wá lọ́wọ́ láti ṣe àwárí àlàfíà àtinúwá kí á sì mú ìgbàgbọ́ wa nínú Rẹ̀ pọ̀ síi.

Jésù Krístì sọ pé: "Nkan wọ̀nyí ni mo ti sọ fún yín tẹ́lẹ̀, kí ẹ̀yin kí ó lè ní àlàfíà nínú mi. Nínú ayé ẹ̀yin ó ní ìpọ́njú: ṣùgbọ́n ẹ túјúká; mo ti ṣẹ́-gun ayé" (Jòhánù 16:33). Ní jíjẹ́ ẹ̀rí ti òtítọ́ náà, Linda S. Reeves, Olùdá-mọ̀ràn kejì nínú àarẹ gbogboògbò Ẹgbẹ́ Ìrànlọ́wọ́ sọ pé: "Olúwa ti kún fún àánú sí mí Ó sì ti ràn mí lọ́wọ́ láti mú àjàgà mi fúyẹ́. Ó ti ràn mí lọ́wọ́ láti ní ìmọ̀lára àlàfíà ńlá."[2]

Alàgbà Richard G. Scott ti Iyejú àwọn Àpọ́stélì Méjìlá kọni pé: "Ibi tó yẹ fún . . . àlàfíà ni, nínú ilé ara wa, níbití a ti ṣe gbogbo ohun tí a lè ṣe láti mú kí Olúwa Jésù Krístì jẹ́ àárín ẹ̀là."[3]

### Àfikún Àwọn Ìwé Mímọ́

Ìsàíàh 9:6; Lúkù 2:14; Jòhánù 14:27; 1 Nífáì 13:37; Ẹ̀kọ́ àti àwọn Májẹ̀mú 59:23

### Láti inú Àwọn Ìwé Mímọ́

Ìsàíàh sọ àsọtẹ́lẹ̀ nípa ìbí ti Jésù Krístì, Aládé Àlàfíà (ri Ìsàíàh 9:6). Ní Àméríkà, Sámúẹ́lì ará Lámánì sọ àwọn àmì tí yíò wá pẹ̀lú ìbí ti Krístì ní ọdún márùn lẹ́hìn náà (ri Hẹ́lámánì 14:3, 5). Bí ọjọ́ àsọtẹ́lẹ̀ ṣe nsúnmọ́, àwọn aláìgbàgbọ́ ṣe ìdérùbani láti pa gbogbo àwọn Onígbàgbọ́ tí àwọn àmì wọ̀nyí kò bá ṣẹlẹ̀. Wòlíì Nífáì "kígbe kíkankí-kan pe Olúwa ní gbogbo ọjọ́ náà; àti kíyèsíi, ohun Olúwa sì tọ̀ọ́ wá tí ó ńwipe: . . . Ní ọ̀la ni Èmi yíò wá sínú ayé" (3 Nífáì 1:12–13). Àwọn àmì náà jáde, àti pẹ̀lú ìbí Krístì, "àwọn ènìyàn náà tún bẹ̀rẹ̀ sí ní àlàfíà lórí ilẹ̀ náà" (ẹsẹ̀ ìkẹtàlélógún)

Ní Bẹ́tlẹ́hẹ́mù, Màríà "bí àkọ́bí ọmọkùnrin rẹ̀, ó sì fi ọ̀já wée, ó sì tẹ́ẹ sínú ibùjẹ́ ẹran" (Lúkù 2:7).

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁŃPẸ́**

1. Quentin L. Cook, "Àlàfíà ti Ara-ẹni: Èrè ti ìṣòdodo," *Lìàhónà,* Oṣù Kárún ọdún 2013, 35.
2. Linda S. Reeves, "Gba àwọn Ìbùkún ti àwọn Májẹ̀mú Rẹ," *Lìàhónà,* Oṣù kọkànlá. ọdún 2013, 120.
3. Richard G. Scott, "Fún Àlàfíà ní Ilé," *Lìàhónà,* Oṣù Kárún ọdún 2013, 29.

### Gbèrò Èyí

Ní àwọn ọ̀nà wo ni Olùgbàlà ti mú àlàfíà wá sínú ayé rẹ?

© 2014 Nípasẹ̀ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ ìtumọ̀: 6/14.
Ìtumọ̀ ti *Visiting Teaching Message, December 2014*. Yoruba. 10872 779